# ORO OKE - QDE D'OSU O LEKENKA



AWOGBA
Omode fun
Giri, Eyi,
Hiku-ekin,
Orere.
Ra Tire Ni
Ile Egbogi
— ISE —
Olodumare
Okebola,
Ibadan,
116, Great
Bridge St.,
LAGOS



ELETI OFẸ
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



TO CLEAR
Gents Suede Court Shoe
Brown, Black & Grey
Before 42/6d Now 32/6d
Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
10A, Moloney Bridge St.,
LAGOS.



VOL. VII No. 446. ELETI - QFẸ LAGOS, SATURDAY, DECEMBER 17, 1955. KQBQ MEJI (2d.)


## Qro Ilu Oke Qde D'osn O Lekenka

### ẸGBẸRUN IRQ KOLE BORI OTITQ KAN

(1) Mo fẹ sọ fun Ogbẹni S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ, ti o sorọ sinu Iwe Irohin Ele.Qfẹ ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu kejila ọdun yi. Ti o sọ bayi wipe:- Baba iya on ni o tẹ Oke-Qdẹ do. Irọ ni mori ọrọ na si Patapata Inu mi yio dun pupọ ti o ba le lọ bere itan Oke-Qdẹ lọwọ Baba iya rẹ to sọ fun pe, on ni on tẹ Oke-Qdẹ do. Nitoripe Irọ gba a ni. Ogbẹni S.O T. Tẹlẹdalaṣẹ pa ti o sọpe Baba iya on ni o tẹ Oke-Qdẹ do.

Baba mi agba ti orukọ rẹ njẹ Maku ni o tẹ Oke-Qdẹ do. Ti Ogbẹni S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ ba fẹ mọ daju pe Maku ni o tẹ Oke-Qdẹ do, ki o lọ wa Iwe itan Oke-Qdẹ, mo si tun fẹ sọ fun Ogbẹni S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ wipe mori ka ninu iwe itan Oke-Qdẹ wipe Maku, ẹni ti iṣe Baba mi agba ni o tẹ Oke-Qdẹ do, ati wipe wọn si tun pani itan fun mi pe Maku ni o tẹ Oke-Qdẹ do.

(2) Inu mi yio si tun dun bakanna ti Ogbẹni S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ ba le sọ orukọ Baba iya rẹ ati iru iṣẹ ti Baba iya rẹ nṣe sinu Iwe Irohin Eleti-Qfẹ fun gbogbo agbaiyeka.

(3) O yami lẹnu wipe, mo wadi orukọ Ogbẹni wa S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ lọwọ awọn gbajumọ gbajumọ ti iṣe ọmọ Ibilẹ Oke-Qdẹ, ṣugbọn wọn sọpe awọn ko mọ ọ larin ilu Ok-eQdẹ ati ni Eko yi. Mo wa gba Ogbẹni S O T Tẹlẹdalaṣẹ ni iyanju pe kio fi abisọ orukọ rẹ ati iru iṣẹ to nṣe sinu Iwe Irohin to ba ma fesi, bikobaṣebẹ, alejo ni o jẹ ni Ilu Oke-Qdẹ, ki iṣe Onile.

Mo da ọrọ ti S.O.T. Tẹlẹdalaṣẹ duro bẹ, mo nreti esi o.

(4) Mo wa dupẹ lọwọ awọn alagba wa ati awọn ọmọ-kunrin ati awọn Qmọ-binrin to wa ni Eko, ni Ibadan Ile-Ifẹ, ati ni Oke-Qdẹ gẹgẹbi afẹnu ṣọkan lori Ogbẹni wa, Bello Qlapinni Oyinloye, bi ifẹ ti ẹni si.

Emi ni,

G.A. Maku EKO.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Qna tara ti enia legba lati
di onisowo nilẹ Nigeria wa.
ni ile Ifowopamọsi ti NATIONAL BANK
Ẹnikẹni ti o ba fẹ kan ogunlọgọ
aimọye awọn onisowo ilẹ Nigeria lara.
yala lati ma ta ọla fun wọn ni,
tabi lati ma ra awọn ohun ọgbin ilẹ wa
ki o lọ si NATIONAL BANK

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWQN AṢOJU WA NILU QBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## Gomina Gbogbo-gbo pe Ipade awon Ogunna Gbongbo

O ta si wa leti fẹnrẹn wipe Qlọla Gomina Agba Sir James Robertson pe ipade awọn Gomina ipinlẹ kọkan, pẹlu awọn Olugbimọ wọn fun ipade ni ọjọ karun osu January, 1956, fun aṣaro l'ori ipade nla fun eto ilu ti nwọn yio ṣe ninu ọdun ti o mbọ. A si ni eto wipe awọn Alakoso Ijọba Mẹtẹta ni yio peju si ipade na.



OLOYE AWOLQWQ

A gbọ wipe ohun ti nwọn nfẹ ṣe ipade yi le



GOMINA AGBA

l'ori ni lati jiroro ibiti ao se ipade ati iru awọn enia ti yio tọ lati peju-pesẹ si ipade ti eto iṣelu tantun ti ao tun ṣe na. Qlotu ijọba Kamarun yio wa si ipade na pẹlu.

## Olugbimo Kekere Wo Itimole

A gbọ wipe Ogbẹni O. Oweh ti iṣe Akọwe Alabojuto Owo (Trade) ati iṣẹ ni Adajọ R. O. Gaji fi si Itimọle fun iṣẹju Mẹdogun ni Kọtu Yaba ni ọjọ alamisi ọsẹ yi.

A gbọ wipe Ogbẹni Oweh nilati wa jẹ ẹjọ kan ti o pẹ lẹhin ki o to de Kọtu ni Adajọ ṣe timọle fun iṣẹju mẹdogun na

Adajọ si gba iduro rẹ lẹhin ti o sọ wipe on ko jẹbi ẹsun na.

## Owe Yoruba

Isu parada o diyan,
Agbado parada o d'eko,
Iwe Irohin Eleti Ofe
parada o di kosemaka
l'osese

## E Fi Obirin Sike Qba Obirin

Eyi yio je ohun idunnu nla kan fun Qba ilu Oyinbo, bi Alase Ijoba ilu Eko, ba le se eto ipade Qba-binrin ilu Oyinbo ti o nbo yi pelu awon Alakoso Ile-Eko, fun a ti yonda awon Qmobinrin Ile-Eko ki nwon wa pade Qba na.

Ki awon se eto na lati ori qmo-qdun mewa tabi qmo qdun mefa titi de ori awon agbalagba inu won ki, nwon wa ninu aso kanna, ki awon to won gegebi nwon ba ti ga si ara won lati isokale Kerem ni Idumota pelu Asia ikini ki nbo lowo won, ki awon Olopa se eto lati jeki awon omo nwon wonyi fo gelerebe l'otun l'osi titi de ile ti ati pese sile fun Qba na.

Eyi ni imoran temi fun ipade Qba ilu Oyinbo.

EFQNA-HAN MI

Enyin Ojogbon Okowe "Fleti-Qle" E fi ohun ti a je se lori ibere mi yi han mi.

Iya kan wa, O bi omokunrin kan, omo na fi Iya re sile o lo si idale ko pe ti Qmo yi lo, Oju Iya re fo, Eti re di, Qmo yi de idale ko p'ojo ko p'osu to de idale o ku. Kini ati se le t'ufo fun Iya re?

Mo nreti esi o.

Emi ni

Adenuga Adefarakan

Eko.

## Orisirisi Ijo Ile Yoruba

Lati Owo Opeie

Orisirisi ni awon ijo ti o mbe ni ile Yoruba, bekanna ni ilo won se yato si ara won,

Abitub je ilu ti awon ofi owo lu ti nwon si ngbe koran ijo re fere dabi ti Agbe, sugbon o le die jalo.

Abete je ilu kan ti nwon nlu ni ile Yoruba lasiko ti awon ijoye tabi Qba ba nse awuye-wuye ijo re fere jo ti kete sugbon ko le tobe.

Agidigbo je ilu ti a ma nlu ni asale nigbati nwon ba nsere alo pipa ele ati faji ni ijo re owe ni won si fi npa.

Dundun je ilu ti Baba Alafin Qyo ma fi nse ola faaji ni ijo re ti nwon ba nlu u, awon ologbon lo mbo ohun ti o nwi Nwon lu ilu yi fun iyawo tabi fun oku

Apon'on Ilu Dundun ni nwon fi nlu ilu yi, sugbon ilu ati ijo re yato si Dundun, ijo re si mu pakanleke dani

Gangan ilu yi ni awon Dankere omokunrin ma fi nda ote sile, lati mu enia se ohun ti ko fe latise yala ni Ijoye tabi Qba On ni a si nlu fun awon jagunjagun

Agbe tabi Sekere je ilu ti a nlu fun awon Opidan ko si si ere ti o le bori ilu Agbe; ijo re fere jo ti Bata

Kete je ilu kan ti ijo re mu pakanleke dani awon Alugbara lo njo ti nwon o si ma dara

Bata je ilu kan ti a se gboro-gboro o si je eyiti a nlu fun Egungun ati ori sa pakanleke ni ijo re

Sakara je ilu kan ti o sese hu ni titun yi lodun 1920 ni ilu yi bere ni akoko de re bi enia ko ba tiro ko le jo o sugbon nisisiyi o ti di ijo faaji.

Orunsa je ilu ti won nlu nigbati nwon ba taporogan ninu Osupa.

Gbedu je ilu ti a nlu fun Qba ati Ijoye

Aran si je ilu ti a nlu fun Gelede

Batakoto je ilu ti Danmole da sile fun awon egbe Onigele Aremo Eko


**Enjoy Your Own**

**— Songs —**



Songs By Your Own People in the way you love masterly rendering of additional AFRICAN MUSIC is yours, on obtainable from :

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers ....**

THROUGHOUT ....... ..... NIGERIA..


## Alakoso Ijoba Ariwa (North)



SARDAUNA SOKOTO

Aworan inu iwe wa yi niti Qlola Ahmadu ti ise Alakoso Ijoba Ariwa (North), yio wa si ipade ti Gomina agba pe fun ijiroro lori ipade nla ti odun ti o mbo yi, a ko le so iye awon Qlola Olugbimo ti yio wa s' ipade na pelu Qlola Sardauna Sokoto yi.

Ki Allah mu ojo ro o

Awon enia ilu Oke-Qya na nf'oju s'ona nisisiyi fun alejo pataki, Alaiyeluwa Qba Obinrin pelu eni-Qla Oko re ti o mbo wa be wa wo ninu odun ti o mbo.

## Alakoso Ijoba Ila-Orun (East)

**Aworan inu iwe wa yi niti Olola Dr. Nnamdi Azikiwe ti yio wa si Ipade ti Olola Gomina Agba pe fun ijiroro lori eto fun ipade nla odun to mbo**

**Enyin okawa wa yio ranti wipe Olola Nnam- Azikiwe yi sese pada de lati ilu awon Oyinbo ati Amerika ti o ti lo lati bi osu meta ni**



Dr NNAMDI AZIKIWE


## Western Region Production Development Board

CLERK OF WORKS

The Board invites applications for the post of Clerk of works who will be responsible for the inspection, maintenance and repair of buildings.

Candidates should have served a full apprenticeship in one of the Building trades and served as General Foreman or Contractor's Agent on large Contracts, or have had previous experience as a Clerk of works.

Salary to be paid will be depend upon qualifications and experience of the successful candidate and will be in the range of £780 to £1,470 per annum (inclusive of Expatriation pay where applicable). Point of entry will depend on the candidates qualification and experience.

Applications, in the applicants own handwriting, giving full details of qualification and experience, should be forwarded to:

The personnel Secretary,
Western Region Production Development Boad.
Ibadan,

to reach him not later than the 21st December, 1955.

## Orunmila L'a Npe Ni Ekun Amude Soju

Lati Ọwọ ẸSỌ IKOYI

Ọkanran meji 'awo ti o da fun Ọrunmila, Ti o si bu fun gbogbo Irumọlẹ, Lọjọ ti nwọn mbọ wa sile aiye, ti nwọn nj jakadi wipe, Tani yio ṣe agba nigbati nwọn ba de ọhun, A ni ki gbogbo wọn tilẹ duro se etutu, ki nwọn ba de Ile aiye na, Keregbe kan, aji-wọn kan, ati ẹgba a owo ẹyọ ni ẹbọ Ọrunmila ni-kanṣoṣo lo gbọ, ti o si rubọ ti o si rubọ ninu gbo-gbo wọn Ọkanran meji. Nigbati Olodumare ti yan awọn Irumọlẹ ti yio lọ sile aiye tan, oju wa bẹrẹ si kan wọn lati tete de ile aiye. Nitoripe ẹnit o ba kọkọ de ọhun ni yio jẹ agba tabi olori fun gbogbo irumọlẹ

Ọkanran - meji wa tẹ Ifa silẹ, o wi fun gbogbo awọn Irunmọlẹ ti o nlọ sode aiye wipe. gẹgẹbi odu ti o yọ fun wọn nipa ile aiye t nwọn nlọ naki nwọn duro rubọ nitori ki nwọn le de ile aiye na, laisi idagiri ọna. Awọn Irumọlẹ nwọnyi ko tilẹ duro feti si ohun ti odu Ifa Ọkanran - meji yi nwi. Olu-kuluku wọn ndi ẹru pa, pa, pa, nwọn njijakadi lati tete de ile aiye. Ṣugbọn akọ Ẹkun n'a kan ti lọ bọ s'oju ọna de wọn B ọkọkan ninu awọn Irunmọlẹ yi ti nyọ si lọwọ bẹni o nki wọ mọlẹ ti o si npa wọn jẹ titi o fi pa gbogbo wọn jẹ tan porongodo, o wa ku Ọrunmila nikan lẹhin. Ki o to di wipe Ọrunmila dide o duro tubọ, o si ṣe etutu ki o to bọ s'oju ọna irin ajo rẹ

Ṣugbọn ki o to de ibiti ẹkun nla na lugọ si ojo nla kan rọ, ti o si ṣan agbara gidigidi, Ojo yi lo le Ẹkun na kuro nibiti o lugọ si, ko mọ igbati Ọrunmila kọja sile aiye

Nigbati ojo na da tan, o tun pada wa lugọ de Ọrunmila, nigbati o de aye rẹ Ogborun Ọrunmila wipe o ti kọja sile aiye, o bẹrẹ si lepa rẹ bọwa sile aiye, o si ba Ọrunmila ni igboro Ifẹ Oyelagbo ki o to de ibiti yio wọ si.

Ọrunmila fura, o si kofiri Ẹkun na, o mura ija silẹ dee, Bi Ẹkun na t ri o fo fẹrẹ lati bo Ọrunmila mọlẹ, bẹ l o fi ajiwọn ọwọ rẹ ṣe Konge rẹ, o yi i mọ Ẹkun na lori, o di i, o si gberu. Ayani. ori i, akọkọ ti ao kọ fi oju ri Ọrunmila nile a'ye, ti on ti aye ẹkun ni. On pẹlu rẹ na ni a fi wọ sinu ile kanna, tobẹ ti ile Ọrunmila fi di ile Ẹkun, o si di ẹru jẹjẹ fun gbogbo ọmọ araiye.

Nigbana bi ọmọ araiye kan ba nlọ sile Ọrunmila, bi nwọn ba bi i lere wipe nibo ni o nlọ, on yio dahun wipe "Mo nlọ sile Ẹkun. Bẹbẹ ni Ẹkun di orukọ Ọrunmila tobẹ ti a fi fun ni orukọ yi wipe Ẹkun, a mu idẹ soju Ekanna ko jẹki Ẹkun họra, nitori pe nigbati Ọrunmila nru Ẹkun na bọwa, nṣe lo nfi ẹkanna rẹ gun u lori, apa ekanna ọjọ na ni o mbẹ lara Ikin titi di oni yi. Ẹkun na ni Ọrunmila kọkọ pa bọ Ifa rẹ nigbati o dele aiye.

Awọn Babalawo gba bọ wipe. ọna ti enia le gba sin Olodumare, ti yio si jẹ itẹwọgba lọdọ rẹ, nilati jẹ ọna ti On tikala rẹ ti ṣe ilana silẹ, Bi o si ti jẹ wipe ko si isin ti o pe laini sara, ẹbọ, tabi etutu. araiye ko sile ti kala wọn ronu kan iru ohun ti Ọlọrun fẹ fun ẹbọ tabi sara, ayafi ki Ọlọrun na ti ṣe ifihan rẹ. Bi Olodumare ko ba si gba ẹbọ kan gbogbo isin ti oluwa rẹ ṣe jẹ asan. Ọ yẹ nitori eyi, ki o si dani loju gbamgba pe ẹbọ tabi sara ni koko isin Olodumare.

## The Ministry Of Education, Western Region

VACANCY FOR REGIONAL LIBRARIAN

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Regional Librarian in the Regional Headquaters

2. SALARY: (a) For pensionable officers Scale A; £624 x 36 - £696 £804 x 42 - £1,140 x 48 - £1,380.

(b) For Contract officers: As for pensionable officers plus 10o/o basic salary plus gratuity subject to any Revision that may be made by Regional Government in the light of 1954/55 Salaries revision for Contract Officers

3. QUALIFICATIONS: Candidates must possess either an academic degree and / or professional qualification (LFA) plus suitable experience.

4. DUTIES: Successfull candidates will be required to advise on the planning and organisation of Library Services in the Western Region, take charge of Central Library to built in Ibadan within the next two years and supervise Local Authority and Community Reading Room, and such other duties as the Head of Department may assign to him.

5. OTHER CONDITIONS OF SERVICE:

(1) If an expatriate on first appointment an Outfit allowance of £60 is payable,

(2) The Provision of Government Quarters, where applicable is subject to the payment of rent at 8 1/3 of basic salary.

METHOD OF APPLICATION: In Nigeria: Applications from candidates not in Government Service should be completed in duplicate on the prescribed form obtainable from the Secretary of any of the Regional or Federal Public Service Commissions.

Applications from candidates in Government Service should be submitted through the Heads of Departments and be accompanied by copies of Confidential Reports for the last three years and a covering letter wherever possible containing special comments that may prove of value in assessing the suitability of the candidate for the post applied for.

In the United Kingdom: Applications should be competed in duplicate on the prescribed form obtainable from the office of the Commissioner of the Western Region of Nigeria, 18, Grosvenor Gardens, London, S W. 1, and submitted through the Liaison Officer to reach him by Decmber 26, 1955.

All applications should reach the office of the Director of Recruitment, Public Service Commission, Western Region of Nigeria Ibadan not later than 2nd January, 1956.

Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Ẹlẹti - Ọfẹ

# ELETI ỌFE

A-NJU-WÖN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

29, Kosoko Street Lagos "ELETI - ỌFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23379

VOL VII NO 446 LAGOS, SATURDAY DEC 17, 1955.


## Ijoba Iwo-Orun Pegede

Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ fi gbọrọ jẹ'ka, ninu ipade ti nwọn bẹrẹ si ṣe ninu ọsẹ yi, ninu ile Igbimọ Aṣofin ti ipinlẹ Iwọ-Orun ni Ibadan (Western House of Assembly).

Nigbati Ọlọla Alakoso Ijọba Iwọ-Orun da imọran pataki siwaju awọn Ọlọla Olugbimọ wipe "ki a fi ẹnu s'ọkan wipe a nfẹ Ijọba wa fun arawa (Ominira) ninu ọdun 1956, ti o mbọ yi, ti a gbọ wipe gbogbo awọn Olugbimọ ni nwọn da muso si imọran Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ti Iṣe Alakoso Ijọba Iwọ-Orun na ti nwọn si fi ara mọ.

Eyi fi iṣẹ aik'arẹ awọn ti o mu itọkọ Ijọba wa dani ni Iwọ-Orun han nitoripe gẹgẹbi o ti wa ninu Iwe eto iṣelu wa ti ọdun 1953, ti awọn Alaṣẹ Ijọba wa fi ni ifọkanbalẹ lati gbe iru imọran yi jade, ti awọn ijọ alatako ijọba paapa ko fi ri atako ṣe si. Ogo pataki ni eyi jẹ fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group)

OTITỌ NI YIO LEKE

Niwọn igbati o ti jẹpe otitọ ni awọn Olotu ati awọn akọnijẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) fi ṣe ipilẹ Ijọba wa, ko si bi agbara rikiṣi kan ti le to, ti yio bi i lulẹ, nisisiyi, iṣẹ Olukuluku awọn Ijọba ilẹ Nigeria nfi ara han fun aiye ri. Eyi mu wa kan sara iyin si Alakoso Ijọba wa, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, ki Ọlọrun Ọba Alaye ba wa fun ni okun ati alafia ki o fi ba wa gbe orilẹ-ede wa de aye ti a nle ba.

A kole ṣai ki awọn apa keji wa, (eyini ni awọn alatako) fun lakaye ti nwọn ṣe ti nwọn fi gba imọran na laini abawọn lati ọdọ wọn, eyi fi han wipe otitọ ko ṣe bo mọlẹ.

Iru iwa lakaye bi iru eyi ni ohun ti a nfẹ ki awọn Olugbimọ atako Ijọba wa ma a ṣe fun ilọsiwaju ilu wa, a ko le fi idaru ṣiṣẹ lori imọran rere fun ilu ṣe.

Ijọba Iwọ-Orun pegede o.


ABOKI



TI IWULO RE LOKIKI
yika Nigeria

KOSEMANI lo je fun ilekile
Fun-orisirisi AILERA, atata
Gbogbonse lo je.

RA IGO KAN LONI
nitori AJEBIDAN ni

LODO

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES
Amunigun Street, Phone 189x, Box 295, Ibadan.


## Ipade Egbe Alasowopo (Co-operative) Ti Ijoko

Ni ọjọ kejila oṣu November, 1955, awọn aṣoju Ẹgbẹ Alafiọwọsọwọpọ ti Agege ati ti Coker's Market Ifaw lọ gba awọn Ẹgbẹ ti Ijoko ni Imọran rere, orukọ awọn Aṣoju na niyi:- Ọgbẹni Alex O Williams (Baba Ẹgbẹ) Ọgbẹni M.F. Beckley (Igbakeji Baba Ẹgbẹ) Ọgbẹni J.M. Ọdẹsilọ, Ọgbẹni E.O. Ọbadina ati Ọgbẹni Sadiku Ladele ni dede agogo mọkanla owurọ ni awọn aṣoju yi de Ijoko. Ọgbẹni Emanuel Adeṣina ati S.A. Shodipọ ni o wa pade awọn aṣoju yi ninu Mọto ayọkẹlẹ ti nwọn muwa awọn si mu wọn lọ joko sinu ile Ẹgbẹ.

Ọgbẹni Alex O Williams fi adura kekere si ipade na ninu ọrọ Baba Ẹgbẹ, o se alaye pe ọpọlọpọ anfani ni o wa ni o wa ninu Ẹgbẹ alafiọwọsọpọ, awọn agbẹ ti o ba wa ninu Ẹgbẹ yi yio si ni anfani lati le ta awọn ọja wọn ni ata jere ju pe ki ẹnikan ṣoṣo lọ ta ọja rẹ lọ. Awọn agbẹ ti o ba wa ninu ẹgbẹ yi yio ni anfani lati le ya owo lọwọ (Co-oprative Bank) lati le fi tun Oko wọn ṣe ati orisirisi anfani miran ti agbẹ le ri ki wọn le fi gbe ile aiye pẹlu itẹlọrun.

Baba Ẹgbẹ yi sọ fun awọn ọmọ Ẹgbẹ ti Ijoko pe ki wọn to le ri anfani yi, nwọn ni lati mura gidigidi ati pe ki nwọn si ni ẹmi ilẹ irẹpọ larin ara wọn, bi idawo ba wa, ki ẹnikẹni maṣe fi ori mu, ati pe ki awọn maṣe rọ nipa ọpọlọpọ Ẹgbẹ agbẹ eyiti wọn ti wa ti o si ti ṣubu.

Baba Ẹgbẹ fi ye ipade yi pe Ẹgbẹ ti awọn aṣoju rẹ wa yi, Ẹgbẹ titun ni, Orukọ rẹ ni Nigerian Farmers Union Co-operative Society. Baba ẹgbẹ fi ọkan awọn ọmọ Ẹgbẹ balẹ pe ẹnikẹni ti o ba ṣe aiṣotọ ninu aye ti o ba wa, ọpọlọpọ ijiya ni o wa fun oluwa rẹ. Nipari ọrọ rẹ o ni ki awọn ti nwọn ko iti ṣe oju'ṣẹ wọn yara lati ṣe, awọn ti nwọn si ti ṣe ninu ti wọn ki nwọn ki o mura lati san eyi ti o ku.

Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Eman Adeṣina dupẹ lọwọ awọn aṣoju yi. Osi gba awọn ọmọ Ẹgbẹ ni imọran pẹlu. Ọgbẹni Adeṣina si fi ọkan awọn aṣoju yi balẹ pe awọn ti mura tan lati ṣe atilẹhin nitori pe ilanọ ti Baba Ẹgbẹ ati awọn isọngbe rẹ nṣe nisinsinyi o fi ọkan gbogbo ọmọ ẹgbẹ balẹ.

Ọgbẹni Sadiku Ladele gba wọn niyanju. Bẹ si ni Ọgbẹni G. Akẹju tun ba ọmọ Ẹgbẹ sọrọ iṣiri Ọgbẹni Sani Oyebọla ṣe ọpọlọpọ alaye o si fun ọmọ ẹgbẹ ni imọran rere. Ọgbẹni J.M. Ọdẹsilọ ni o gba awọn ọmọ ẹgbẹ ni imọran kẹhin.

Lẹhina ni Baba ẹgbe, Alex O Williams wa ki Ọgbẹni Eman Adeṣina pe oku ori re ipo Councillor ti ilu Ijoko ti o bọ si lọwọ ni aipẹ yi. Alaga si gbadura fun pe ki Oluwa o fun ni ọgbọn ati oye ti yio fi le tọju aye na dada.

Lẹhin ipade yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ Ijoko fun awọn aṣoju yi ni mimu ati jijẹ ki wọn to ma lọ pada si ile wọn ni dede agogo mẹrin irọlẹ

Awọn ti wọn wa si Ipade na ni yi Mr E. A. Adeṣina S. A. Sodipo J. S. Akinọla K. F. Abidami, G. Akẹju, E. Ẹnitan, Yesufu Egunleti, Oyebọla, Bisiriyu Afuwapẹ, Jacob Salada ati Jacob Aiyelẹsọ.

## B'Olubadan Ba Ku Tani 'O joye

IBADAN — Oloye Bello Akinyọọla, Ọtun Olubadan ti Ibadan ni a gbọ wipe o ku ni ile rẹ ni Ibadan nigbati o di ẹni adọrin ọdun ni ọjọ aiye rẹ

Ẹnyin okawe wa yio ṣe iranti wipe Oloye Akinyọ yi ni a gbọ wipe Ọgbẹni Adelabu fi l'oye Olubadan l'ọna odi ti Ijọba fi rọ oye na danu, ẹjọ ifinijoye na mbẹ ni Kotu nisisiyi fun ọgbẹni Adelabu.

Oloye Akinyọ yi fi ọmọ bi ogun ati ọmọ - ọmọ silẹ l'aiye ki Allah gbe si afẹfẹ rere.


## Now Available

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS, DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just Write, Call Or
Phone 21372

IKORODU
TRADING
COMPANY

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS
and NEW COURT ROAD
IBADAN

## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ko to tan.

J.A.AJAO BROTHERS
Medicine Store
7. Egerton Road, Lagos

## Irora Ehin Didun

Ọna wosan rẹ niyi.
Niẹ o mọ wipe Kidinrin lo njẹ ki ẹhin ma dun enia? Bi ko ba si ailera fun nibẹ gbogbo idọti ara ni yio ma sọ danu Ṣugbiọn bi nwọn bo nṣe tikọtikọ idọti ara ti o nwọjọ pọ a ma jẹki ẹhin-dun ni.

Aṣe egbogi DE WITT'S PILLS yi lati jẹki Kidinrin ṣiṣẹ. Iṣẹ ti a ṣe egbogi yi fun gan niyẹn, yio wo wọn san tan, yio si mu alafia wa fun oluwa rẹ.



O to iwọn adọta ọdun ti egbogi yi ti nṣe iwosan fun enia ṇ Ẹhin nro. Aimọye iwe ọpẹ ni a ti ri gba kakiri aiye. Lọ ra tirẹ ni ṣọbu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles


## Awon Ajeji Onisegun Oyinbo Wolu

BRAZZAVILLE.— Laipẹ yi ni awọn ẹgbẹ Onişegun oyinbo kan ti o ti fi ara nwọn jin ọmọ enia lode aiye lati panọ arun fọju-fọju ati arun Ogodo ti o wọpọ larin ilẹ Afrika. Orukọ awọn ẹgbẹ na njẹ World Health Organisation.

Nilẹ Nigeria ni a nsọ wipe awọn Afọju pọ si aṣe işẹbẹrẹ lo jẹ lẹgbẹ ti ilu Moroko Ilu na ti a npe ni Moroko yi gbogbo rẹ ni ti tobi ko ju lati ilu Eko si ilu Jẹbba lọ. Ko si ferẹ to lati Eko si Ondo Iye awọn afọju ti o ju wọn ba jẹ di afọju ti nwọn gba silẹ jẹ Ọkẹ mẹtadilogun enia.

Awọn Onişegun oju nwọnyi ti kọja si apa ilẹ awọn Hausa nibiti afọju gbe pọ si ṣugbọn awọn mẹta kan gunlẹ silu Eko laipẹ yi nwọn o si kọja si apa ilẹ Ijẹbu. Işẹ awọn Onişegun mẹta na ni lati wo gbogbo arun Ogodo san, eyiti a gbọ wipe, o wọpọ nilẹ Ijẹbu.

Ko nşe işẹ kekere ni awọn ẹgbẹ Onişegun W. H. O. nwọnyi nşe. Awọn kanna tun nşe awotan arun Ikọ Ẹgbẹ, tabi ẹ ko raiye.


# OVALTINE

**lo nfun mi ni okun**



Lati ma wa oko mi to
je ise alagbara Ovaltine lo
nje ki agbara mi si wa be
Osi njeki nwa ni alafia
ninu gbogbo irin ajo

*Akara Ovaltine pelu!*

*O ladun o si nmu unrun fun onje ipanu igbakugba. Bu die si apo ti eba nlo ibi ise, oni igbadun pupo*




***OVALTINE*** **fun agbara ojumọ!**


## Polowo Ọja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ọfe

## Abdul Mojid Animashaun D'ologbe

Ni ọjọ Tuesday ọsẹ yi ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu December 1955 yi ni Ọgbẹni Abdul Mojid Animashaun ṣe alaisi ninu ile rẹ l'Eko.

Ọpọlọpọ Ọdun ni ologbe yi lo ninu Ibadan gẹgẹ bi Ọga ile ita'ja awọn Oyinbo Ọlowo (C. Gottschalk) o si jẹ Alaga fun awọn ẹgbẹ ti a npe ni Ibadan Turf Club ati Baba ẹgbẹ fun awọn ọmọ ibilẹ ilu Eko to to wa ni Ibadan.

Nibi isinku rẹ ko niye awọn sarakí-saraki enia lati Ibadan, awọn gbajumọ ati awọn enia pataki ozolu Eko peju-pesẹ. Lemọmu agba Alfa Abdul Kerimu Nollah ti Mọṣalaṣi Jimọ nla ni o ṣe isin isinku ologbe Abdul Mojid Animashaun ẹnire na.

Awọn ẹgẹṣin ṣare pẹlu aṣọ alarabara ni orisisi ni nwọn to lori ẹṣin tele o ku rẹ de ite oku Oke-suna. Ologbe yi paapa jẹ ọkan pataki ninu awọn to ni ẹṣin ti o nsare ninu Ibadan, ẹṣin tirẹ ni wọn npe ni NEW GIFT ti gbogbo awọn enia to nlọ si bi ere ẹṣin mọ ni amọdaju.

Ologbe na fi ọmọ mẹwa silẹ aiye, ki allah gbe ni afẹfẹ rere ki ẹhin rẹ dara fun awọn ọmọ rẹ.

## Bashorun Ọyọ Tu Asiri Opuro

ỌYỌ– Oloye Bashọrun ilu Ọyọ St John the Baptist Ladokun sọ wipe irọ patapata ni iwe Irohin kan pa to sọ wipe on ti kuro ninu Ẹgbẹ Afẹnifẹre, (Action Group) on ti wọ Ẹgbẹ Alakuko.

Bashọrun sọ wipe irọ funfun balau ni ọrọ na, Baba-isalẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni on iṣe ni Ọyọ, ati pe lati igbati on ti nro'le dipo Alafin ti ko si nile ni ilu Ọyọ ti tuu, ti o si ba a.

Ẹnyin Oniwe Irohin aturọta-bi-clubọ, otitọ ti faraban o.

## Afikun owo-ase keke omolanke pelu keke ologere

A gbọ wipe awọn Igbimọ Munisipa nṣe aṣaro afikun owo-ṣẹ (Licence) kẹkẹ Omolanke yio di £4 kẹkẹ Ologere yio di 12/6d fun ọdun kan.

Ogun agbọtẹlẹ ki ipa irọ o

## Ikomo To Larinrin

Ni ọjọ ọsẹ ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu December, 1955, yi ni a ṣe ikomọ-jade ti ọmọ ti Ọlọrun fi ta Ọgbẹni Salawu Alao Onigbanjo l'ọrẹ. Ni ọjọ Satide ọjọ kẹta oṣu yi ni Alufa Kamarud-deen wa ṣe wasi a si ṣe isọmọ-lorukọ ni ọjọ ọsẹ, o mirinqindin, ẹnikeji.

Awọn ọmọ mẹta ni a ṣe ikomọ wọn pọ, Alufa Ayileru Ọmọkewu, ni o ṣe eto isọmọ l'orukọ na, o ṣe ọpọlọpọ alaye lori ọmọ ki kojade ti awọn Ogunlọgọ enia to wa sibi ikomọ na si gbadun rẹ.

Alufa Kuranga ni o tun kin lẹhin, asi sọ orukọ awọn ọmọ na ni, Ganiyu Ajao, Ibraimọ Ajani ati Isiaka Iyanda. Ọgbẹni Salawu fi ile pọn'ti o si fi ọna ro'ka ni ọjọ na.

Aburo rẹ, Ọgbẹni Y.A. Akọmọlafẹ ṣe gudugudu meje nibi inawo ni ọjọ yi. ajeti ni ohun jijẹ ati mimu, alẹ ni awọn ọpọ enia na to lọ sile wọn.

Adupẹ fun gbogbo awọn to wa sibi ikomọ na ire yio kari gbogbo wa o. A si ki baba ọmọ ati aburo rẹ Komolafẹ ku inawo, ki Ọlọrun da awọn ọmọ na si o.


A GIFT FROM HEAVEN!
BAMWŌ BABY MIXTURE
OF EXCEPTIONAL VALUE IN PREVENTING SICKNESS, CURING FEVERS, COUGHS, MEASLES AND TEETHING AILMENTS.
ENSURES SOUND SLEEP.
PRICE: 2/6 POSTAGE 1/-
THE EGBA TRADING ARADAN STORES, 144 DENTON STREET, P.O. BOX 2, EBUTE METTA & BRANCHES

GEGEBI ỌDUN KERESIMESI TI MBO YI,

IWO YIO FE SO ILE RE D'OTUN

**Asiko Siwa Lati Se Atunse Re**

**Pelu Ọda:-**

**PAMMASTIC**

**Ọda yi ki isa ni gbogbo igba.**

**SCOA**

EKA SOBU WA MBE NI

GBOGBO NIGERIA.

Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P.O. Box 407 Lagos Phone 23370